## Owó Ìranwọ́ fún Èrò Atinúdá Àwọn Aláwọ̀dúdú: Afárá àti ìkọ́ 2023

## Àwọn Ìbéèrè Tí Àwọn Ènìyàn Máa Ń Sábàá Béèrè

**1. Kini àjọ B3 túnmọ̀ sí?**

**a. Àjọ ti àwọn aṣíwájú rẹ jẹ aláwọ̀dúdú:** Púpọ nínú àwọn adarí ní gbogbo ìpele nínú àjọ yi jẹ́ aláwọ̀dúdú.

**b. Àjọ tó ń sin àwọn aláwọ̀dúdú:** Ìlépa àkọ́kọ́ ti àjọ yi ni o dálórí àtìlẹyìn tí ó ní ìtumọ̀ àti Ìlọ́wọ́sí àwọn àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú.

**d. Ìfojúsún fún àwọn aláwọ̀dúdú:** Púpọ̀ nínú ètò iṣẹ́-ṣíṣé ni ó yan sísin àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú láàyò.

**2. Kò dá wa lójú tí a bá lè ka àjọ wa gẹ́gẹ́ bíi B3 pátápátá. Tó bá jẹ́ pé àjọ wa jé ipa kan tabi méjì nínu ohun ti B3 bèèrè fún ńkọ́? Ṣé ìyẹn túmọ̀ sí pé a ò yẹ ní yíyàn?**

Kókó ìgbówósílẹ̀ ti FFBC ni lati ṣe àtìlẹyìn fun àwọn àjọ ti asíwájú wọn jẹ aláwọ̀dúdú, tí wọ́n mọ̀ọ́mọ̀ ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú ní Canada. A máa ṣe àyẹ̀wò àjọ kàǹkan àti ìwé ìfiféhàn láti mọ bi eto ati àjọ yi bá bá tiwa mu. Gbogbo olùfiféhàn ni wọ́n ní láti ṣe àlàyé bi àjọ wọn ṣe jẹ ti aláwọ̀dúdú àti bí iṣẹ́ wọn ṣe mọ̀ọ́mọ̀ ní ipa ni àwùjọ aláwọ̀dúdú ti Canada.

**3. Ṣé mo lè lo owó ìfilọ́lẹ̀ yi fun iṣẹ́ àkànṣe ni ibòmíràn yàtọ̀ sí Canada?**

Rara. Àwọn àjọ àti ìpilẹ̀ṣẹ̀ tó bá wà ní Canada nìkan ni wọn yẹ fun owó.

**4. Kini alábáṣepọ̀ aláfikún?**

Awọn ẹgbẹ́ alàìláfikún nílò àjọ aláfikun alàìlérè tabi ajo alanu fún ìbáṣepọ̀, láti lè gba owó ìrànwọ̀ lódọ̀ FFBC. Kò pọn dandan láti ni alábéṣepọ̀ aláfikún kí ẹ tó lè fìfẹ́han, sùgbọ́n ẹ máa nílò ìkan ki wọn to lè buwọ́lu owó ìrànwọ́ na.

Àkíyèsí: FFBC kò ní ṣe àtìlẹyìn fún olùfìfẹ̀han tí ó ní àǹfàní si àlàyé síwájú si àti ohun àmúlo nípa iṣẹ́ pẹ̀lú alábáṣepọ̀ aláfikún sùgbọ́n ti kò ní bá olùfìfẹ̀hàn wa alábáṣepọ̀



2 St-Clair Avenue East, Suite 300 | Toronto, ON, M4T 2T5 | forblackcommunities.org

1.833.442.5225 | info@forblackcommunities.org

aláfikún. Fún ipele owó ìrànwọ̀ yii, àwọn àjọ aláìláfikún gbọ́dọ̀ ni alábáṣepọ̀ aláfikùn kí ó to di Ọjọ́ Kẹẹdógún oṣù keji ọdun 2024.

A lè rí àlàyé síwájú sí ni:

a. [Managing an organization](), Imagine Canada

b. [Charities and giving](), Government of Canada

**5. Kìni alábáṣepọ̀ aláfikún ma ń ṣe? Ṣé a nìlò ìkan láti fi bẹrẹ ìlànà ìfiféhàn?**

Alábáṣepọ̀ aláfikun ma dúró gẹ́gẹ́ bíi àjọ tó lófin tí ó ma gba owo dọ́la ti FFBC àti láti tọ́jú àwọn fọ́ọ̀mù owó orí si akanti fún dọ́là na. Alábáṣepọ̀ aláfikun le pèsè àtìlẹ́yìn síi ti olùfìfẹ̀hàn sí FFBC  and alàbáṣepọ̀ bá jọ gbà. O ò nílò láti ní àrídájú nìpa alábáṣepọ̀ aláfikún kí o tó lè bẹ̀rẹ̀ ìlànà ìfìféhan, sùgbọ́n o máa nílò eyọ kan kí a tó lè buwọ́lu owó irànwọ́ fun ẹ.

Ti o bá fìfẹ́hàn láì ni alábáṣepọ̀ aláfikún, mọ̀ wípé o ma nílò láti fi ìwé àdèhùn owo ìrànwọ́ ti a ti buwọ́lù, àti àdéhun ìfọwọ́sowọ́pọ̀ sílẹ̀ lórí àbáwọlé ayélujára.

**6. Ṣe Alábaṣepọ̀ Alàfikún wa Gbọ́dọ̀ jẹ Àjọ B3?**

A mọ̀ wípé ṣíṣàwárí alábáṣepọ̀ aláfikun lè jẹ ìdíwọ̀ fún gbígba owó ìrànwọ̀. Nítorí na, kò pọn dandan fun alábáṣepọ̀ yín láti je Àjọ B3.

**7. Sé Alábáṣepo Aláfikún wa le jẹ Ìsòwò?**

Rara, alábáṣepọ̀ aláfikún yín gbọ́dò jẹ́ àjọ aláìlérè tabi àjọ alanu.

**8. Ṣé mo lè fìfẹ́hàn ju èèkan lọ?**

Rara, olùfìfẹ́hàn ò lè ṣe ju èèkan lọ.

**9. Èló ni Owó Ìrànwọ̀ tó wà nílẹ̀?**

A pe olùfìfẹ́hàn láti fìfẹ̀han ni ipele mẹ́ta.

a. Àwọn Olùfìfẹ́han tó ṣe gbòógì tó sì yára le fìfẹ̀hàn fún owó ìrànwó tó ju $40,000.



b. Àwọn olùfìfẹ́hàn tó fọwọ́sowọ́pọ̀ le fìfẹ́hàn fún owó ìrànwọ́ tó ju $100,000

**10. Tí mo bá yàn láti joko sori Yíyàn Ti Agbègbè Àyíká, ṣé ìyẹn túmọ̀ sí pé mo ma ka iwé ifìfẹ́hàn mi fúnra mi?**

Rara. Olùfìfẹ́hàn tí ó darapọ̀ mọ́ Àyíká Yíyàn ti agbègbè kò ní ṣe àyẹ̀wo ìwé ìfìfẹ́hàn wọn.

**11. A ti gba owó ìrànwọ́ láti ọ̀dọ FFBC tẹ́lẹ̀ rí, ṣe a lè fìfẹ́hàn fún owó ìrànwọ́ yi?**

Bẹ́ẹ̀ni, ẹ yẹge láti fìfẹ́hàn.

**12. A tún ti fìfẹ́hàn fún Ìpìlẹ̀ṣẹ̀ Àtìlẹyìn Agbègbè Àwọn Aláwọ̀dúdú, ṣé a lè fìfẹ́hàn fún owó ìrànwọ yi?**

Bẹ́ẹ̀ni. Sùgbọ̀n ẹ mọ̀ wípé ẹ ò ní lè gba owó ìrànwọ́ fún àjọ kanna.

**13. Nígbàwo ni Yíyàn ti Agbègbè Àyíká ma ṣe ìpinu?**

Ìpinú tó kẹ́yìn máa wáyé ni ìparí oṣù kẹta, ọdún 2024.

**14. Ṣé àwọn àjo ẹlẹ́sìn le fìfẹ́hàn?**

Bẹ́ẹ̀ni, sùgbon àwọn iṣe tó jọmọ ẹ̀sìn tàbí to pẹlú ohun àmuyẹ láti kópa nínu ipele ìgbàgbọ́ kankan kò ní ànfàní.

Àpẹrẹ: Ìjọ ti ó n ṣe okòwò ilé oúnjẹ ní agbègbè le kọwe ìfìfẹ́hàn fún ìpèsè ati owo àwọn òṣìṣẹ́.

**15. Tí mo bá ní ìbéèrè nípa Ìfìfẹ́hàn, tani kí n pè?**

Ẹ ní àǹfàní láti lo booking page láti gba àyè pẹ̀lú àwọn òṣìṣẹ́ wa.



**Atúmọ̀**

Oríṣiríṣi ìṣètò ló wà fún Àjọ Aláwọ̀dúdú àti Agbègbe Aláwọ̀dúdú ni Canada. Owo ìrànwọ́ ti FFBC ni ó wáyé nípasè àlàyé-agbègbè, àṣetúnṣe, àti àlàyé to ni ìdojúkọ. Àwọn ìtumọ̀ to wa ní ìsàlẹ̀ yí yẹ kó fún yín ni òye kíkún lórí àwọn àgbékalẹ̀ wa, wọ́n sì dára ju àwọn àlàyé tí kò ṣe é yípadà lọ.

**Àjọ tó fojúsí àwọn aláwọ̀dúdú:** Púpọ̀ nínú ètò iṣẹ́-ṣíṣẹ́ ni ó yan sísin  agbègbè àwọn aláwọ̀dúdú láàyò.

**Àjọ ti àwọn aṣíwájú rẹ jẹ aláwọ̀dúdú:** Púpọ nínú àwọn adarí ní gbogbo ìpele nínú àjọ yi jẹ́ aláwọ̀dúdú. (òṣìṣẹ́, aláṣẹ, ìṣèjọba)

**Àjọ tó ń sin àwọn aláwọ̀dúdú:** Ìlépa àkọ́kọ́ ti àjọ yi ni ni o dálórí àtìlẹyìn tí ó ní ìtumọ̀ àti Ìlọ́wọ́sí àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú.

**Àdéhùn oní ìfọwọ́sowọ́pọ̀:** Àdéhùn tí a kọ sílẹ̀, tí ó ṣe àlàyé ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ lóri ìdì àti irú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ tí ẹ ní, tí ó sì ní ojúse àti àwọn ipa ti oníkálukú ńkó, ìdí ìfọwọ́sowọ́pọ̀, àdéhùn lóri iṣẹ́ ṣíṣe tí ó ní bí ẹ ṣe ń ṣe ìpinnu àti bí ẹ ṣe ń kojú rògbòdìyan tó bá wà. Àdéhùn yí ni gbogbo ọmọ ẹgbẹ́ tó fọwọ́sowọ́pọ̀ lóri ìfiféhàn fún owo ìrànwọ́ ti FFBC ma buwọ́lù.

**Àṣàyàn Iṣẹ́-ṣíṣẹ́ ti Òṣèlú:** Wònyí ni àwọn iṣẹ́ tí a gbé kalẹ̀ láti ṣe àtìlẹyìn tàbí ìtakò fùn ẹgbẹ́ òṣèlú, aṣojú tí a dìbòyàn, tàbí Olùdíje fún iṣẹ́ ìlú.

**Àwọn Àfojúsùn Ìgbédìde tó ṣe ń tójú:** Àwọn àfojúsùn tó se ń tójú nọni ìpè kíakía tí ó jẹ mẹ́tàdínlógún fún ìgbésẹ̀ èyí tí o jẹ́ ìgbékalẹ̀ láti ọ̀dọ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ àwọn ìpínlẹ̀ United Nations. Àlàyé tó  tẹ̀síwájú ni a lè rí níbí:  https://sdgs.un.org/goals

**Àwọn Ìpinnu Àwùjọ lórí Ìlera:** Gẹ́gẹ́ bi àjọ ti ètò ìlera Àgbáyé (WHO), àwọn ìpinnu àwùjọ lórí ìlera ni "àwọn okùnfa tí kìí ṣe ti ìṣòògùn tó ní ipa lóri àbájáde ìlera." Àlàyé tó tẹ̀síwájú ni a lè rí níbí: https://www.who.int/health-topics/social-determinants-of-health#tab=tab_1



2 St-Clair Avenue East, Suite 300 | Toronto, ON, M4T 2T5 | forblackcommunities.org

1.833.442.5225 | info@forblackcommunities.org